# AWON WOLE-WOLE KAN OWO TABUA NINU ILE





ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI'L'EJỌ






VOL. IX No. 533. ELETI - ỌFẸ LAGOS, SATURDAY, AUGUST 17, 1957. KỌBỌ MEJI (2)


## Esin Imale ko posi lati fi sin'ku

(Lati ọwọ T. K. Oṣiṣi)

Alagba.

Yio dun mọ mi bi ẹ ba le gbamì laye lati ṣe alaye diẹ fun awọn ọkawe rẹ sinu iwe irohin rẹ oniyebiye yi

(1) Otitọ, gbogbo iwe ni o sọ wipe ọjọ mẹfa ni Ọlọrun fi da aiye on ọrun, Bawo ni o ti ṣe wa jẹ ọjọ meje?

(2) Nitoto ni Kabeela pa Abeela, nigbati o ngbe kiri ti ko si mọ bi yio ti ṣe, Imọ wa lati ọdọ Ọlọrun fun u bi yio ti ṣe. Nipa bayi, o si wa ile, o si bo arakunrin rẹ mọ ile na, kini iṣe si yẹn ko wa?



ALUFA T.K. OṢIṢI

(3) Ninu Adamọ tabi gbogbo ohun ti o ti mbẹ tẹlẹ ewo ni a da ṣiwaju? Gbogbo wa la mọ wipe Ọlọrun ti da ohun gbogbo ki o to wa da Adamọ gbẹhin. Adamọ ni Ọlọrun wa fi jẹ ọba lori awọn ẹda yoku. Kilo mu ọrọ yi wa nipe awọn enia isinyi ma nsọ wipe ko si ipl ni aiye atijọ. nitori eyi, awọn ko si le kan posi lati fi sin oku, ọrọ na ko jẹ bẹ rara, awa wi ni. Nitorina Ọlọrun fi Ẹsin Islam lelẹ fun irọrun, ko ma ṣe jẹ inira, ṣugbọn ọmọ araiye fi irọrun silẹ nwọn gba inira mu, Ẹsin Islam kọ wa ni ire ara ẹni. Bi a ba wo Alukuran ori karun, ẹsẹ 30. Gẹgẹbi Ọlọrun ti fi kọ Kabeela bi yio ti ṣe sin oku arakunrin rẹ ni ijọsi, o fi eyi ṣe alaye ati ilana, bi o ti ṣe fẹ ki a ma sin oku wa, ṣugbọn awọn eni isinyi fi iyẹn silẹ, nwọn gba inira mu, Ibiti o ti nwa owo posi, owo aṣọ owo nkankan, wahala a wa pọ fun u, ẹkun a si di meji fun a. Bi o ti sun ẹkun oku, bẹni yio tun ma sunkun owo oku ti ko ri. Ọlọrun si ti sọ ninu ọrọ rẹ pe ohun ti on Ọlọrun ba fi ran enia ni on (Ọlọrun) yio ma ran a lọwọ si. ṣugbọn loni ohun ti Ọlọrun fi jẹ Keferi ni iya ni awọn Musulumi ngbe dani nitori ọrọ Ọlọrun (Koran) sọ bayi pe "wa kathaika Zuinọl kafiruun amọh Kanu yaa mọhiuuna" itumọ gẹgẹ bayi ni a ṣe iṣe awọn Keferi lọṣọ fun nwọn nibi ohun ti nwọn ṣe, ti o ajọ awọn loju pe awọn ṣe dada. A fẹ ki ẹnyin Musulumi tẹle ilana Anọbi nyin Muhammad (S.A.W.S.) nitori koiti si ninu Iwe Ẹsin Islam pe kia ma fi Posi siaku wa bi ọwọ nkan nwọnyi ba yọ. (1) Tia ba wa ninu ọkọ oju omi ti a kosi ti de ibiti anlọ. (2) Ti ilẹ ibiti ao sin oku na si ba jẹ amijẹjẹ (3) Ti a ba fẹ hu


(Wo iyoku loju ewe kẹjọ)


## Awon Wolewole kan owo tabua ninu ile

EKO. Odidi oru [Kotọpo] owo nla meji ni awọn ti o nwole ni Richard's Lane, Oju Ẹyari, ninu Eko kan ninu ile ile ologbe Gbangbose ni owurọ ọjọ Jimọ [Friday] ọjọ 16/8/57, nigbati nwọn nhu ilẹ ile ologbe yi.

Ile ti awọn wo yi jẹ ọkan ninu awọn ile ti Ijọba owo ... Eko fun ... ile Eko ṣe. A gbọ wipe oriṣiriṣi owo bi owo Gold alapapọ 21/- ati owo Padaka ni wọn ri ninu awọn oru wonyi. Awọn ọmọ ologbe na si pejupesẹ si idi owo yi.

Bi a ba ti tun gbọ ọrọ na si a o ma fun yin lomitoro rẹ jẹ.

## Omo Oyekan tun fe gbe ejo Iga Idunganran dide!

Ọmọ'ba Adeyinka Oyekan ma tun de o, o ni on fẹ tun ro ẹjọ oye ọba ti Alaiyeluwa Ọba Adele Keji ti jẹ, wipe ko ni ẹtọ lati ma pe ara rẹ ni Ọba Eko, nitoriwipe idile Ọba Dosunmu ni nwọn fi oye ọba Eko da l'ọla, ati pe Adeniji Adele ko nṣe iran ọba Dosunmu.

Ekeji ti o tun wi nipe yiyan ti nwọn yan Adeniji Adele fi jẹ Ọba Eko tọ sana, ko si ba ofin ati aṣa iṣẹdalẹ ilu mu, nipa bẹ ko ni ọwọ lati ma gbe inu Iga Idunganran.

O si nfẹ l'ẹjọ wipe ẹnitì o ni ẹtọ lati gbe inu Iga Idunganran ni ẹniti o ba jẹ olori ile Dosunmu, on ni o le lo orukọ oye Ọba Eko ti awọn fi da ile Dosunmu l'ọla.

adajọ ti da Oyekan lẹbi bayi wipe:- Gẹgẹbi, ẹri ti o wa ṣiwaju mi, mo gba wipe lati asiko Ọba Gabaro to fi kan Faloiu, ẹnit i


(Wo iyoku loju ewe kẹjọ)


KILO BA YI WA?

Ọpọ enia l'o ni ero wipe bi ko ba si nkan miran nidi ọrọ yi, ki l'o tun nya ọmọ Oyekan lara lati tun gbe ẹjọ miran dide, boya ewẹ. owo ni o nyun lara ti ko si mọ ibiti y'o na a si.

Nitl ẹjọ Iga Idunganran, ni Kotu Gaaran l'Eko nina ọdun 1951, ni



ỌMỌ'BA A. OYEKAN

## Pele Ko Nmu Egbo Jina

E ba mi rerin die ho ho ho ha ha ha hun hun han Ore mi! jowo so fun wa kilo fa idi erin re yi?

Te! o wi ko, mo niran ohun kan ti o sele ni sobu na, ni mo ri okunrin ti o wa sodo obinrin kan ti o nta wosi-wosi ninu sobu, sugbon nitori ti awon ti o fe ra oja si po, o gbe aga fun okunrin na lati joko lehin kanta titi on yio fi da awon onibara re lohun tan.

Okan ninu awon enia na fe ra apoti akara jojo, apoti nwonyi wa loke ibiti alejo na joko si, obinrin na paşe pe ki awon lo gbe apoti kan wa.

Omo'do obinrin na ko le se fun alejo pe ki o yago, o lo yogi iati fi re lule. Beni apoti akara ba bo lu alejo lori.

Obinrin onisobu na bojn wo ehin, o si ba omo ode wi pe, kini se iwo omo yi, o se ara re, Pele o Jare! Alejo na si dahun pe Ehen, se pele lo nmu egbo jina? Ha, he, ha, he, he, he, hi, hi, hi.

## Akiyesi Pataki

A fi eyi kede fun gbogbo enyin Asoju Iwe Irohin wa ni ile Yoruba, l'oke Oya, nile Ibo, l'oke Okun ati nile Oyinbo wipe enikeni ti ko ba fi owo ranse, ao ko oruko re fun Loya Eleti Ofe, ao ba se ejo ao si gba owo irin ese lowo won.

OLOTU


## Kere o!

A ti 'ni origirisi ogun German to sese de, fun oniruru aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra ti'e, k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORES
7, Egerton Road, Lagos.


## AKIYESI PATAKI

**Enikeni ti o ba fe ra Iwe Irohin Eleti - Ofe Ki o lo si Idi Moto, Ogunpa, Tabi Lodo Asoju Wa, Ni 107, Oke Padi, l'egbe Sosi Aguda Nilu Ibadan.**




Awon gbajumo enia gba wipe bi mo ti je oga Ako-ile, mo mo nkan ti awon enia fe, mo si le so wipe Oti Star ni enikeni feran ju.

O da mi loju; ko si eniti ole m'oju kuro ninu adun Oti Star; o dara to be ge, o si lagbara pelu. Tabi iwo yio tun fe si i?



# STAR



ỌTI STAR

l'o je eyiti odara ju! Beni Sammy Sparkle wi.

Awon ehun elo to darajulo



ni afise, Eso oka barley to l'orun daradara ni a fi se Oti Star, awon enia ti o loye lori pupo l'e nsise Oti Star, omo, o si ni awo to yayi.

Oti Star npa orugbe; adun re ko si legbe.

## Imoran Fun Omo Oyekan

Imọran ti o yẹ ki a fun ọmọ Oyekan ni wipe, ki o lọ mọ ọba ni agba, nitori awọn ẹgbẹ Alakukọ ko mba ẹni gbe ọmọ ye, bi awọn ba tẹ ọwọ enia bọ ṣolọ tan, wọn a si pada lẹhin rẹ.

A tun ngbọ finrin-finrin lẹnu ara awọn ajakukọ wipe ẹjọ ti igbimọ Privy Council da fun wọn lori ọmọ Oyekan, ko tẹ wọn lọrun awọn si nṣe eto lati gbe ẹjọ na lo si U.N.O. Maṣe gba ti wọn gbọ,, ma ma si jẹki nwọn tẹwọ rẹ b ọ ṣọlọ. Ranti gbogbo owo ti o ti na danu tabi Enia ha le fiyanju ṣe bi agba nigbati Ọlọrun ko peni baba ? O ti yọ ki eyiyi ye ọmọ Oyekan wipe Ọrun ni Adele ti mu ori ọba wa si aiye, O tọ ki o mọ Ọba ni Ọba.

Ọmọ Oyekan rojọ ni ilu Eko, ko ta, o pe awọn adajọ ilu Saro, Ghana ati ti Eko jọ, o fi ọrọ rẹ lọ wọn, ẹjọ rẹ jẹbi. O tun gbe ẹjọ rẹ fẹrẹ, o di ilu oyinbo, nibiti ofin ko gbe mọ ẹni-ọwọ, aṣẹhinwa asẹhinbọ, awọn ni ẹjọ ẹbi ni ọmọ Oyekan pe.

Ninu kotu ilu Oyinbo yi, a ti gbọ wipe, nwọn ko nṣe idajọ fun ẹnikan ki oluwa rẹ tun sọ pe ko tẹ on lọrun ṣugbọn Ọmo Oyekan sọ wipe nwọn ko ṣe ẹjọ on gẹgẹbi o ti tọ nitorina on fẹ ki nwọn tun tẹjọ na ro.

Awon oyinbo ṣa ni suru jojo, nwọn gba laye lati wi eyiti o fẹ. O tun rojọ sọtun o ro si osi, ohun kanna ti o ti wi na lo tun nwi nigbana ni awọn ogunna gbomọbo na ba tun fa iwe ẹjọ na ya patapata laiki pe Loya Ọba Adele lati fesi. Nwọn ni ki ọmọ Oyekan lọ san owo iriu ẹsẹ fun Ọba Alaiyeluwa Adele Keji.

Kabiyesi Ọba Adele, k'ade pẹ lori, ki bata pẹ lẹsẹ.

## Awon Oniwe irohin ile Nigeria nilu Oyinbo



Awon Oniwe irohin ile Nigeria, ti ijoba yan lati lo wo ile ibiti agbe ti nkan oko ofurufu nilu Bristol, ni odun 1954, ati lati lo ye aragbabu oko ofurufu kan ti nwon sese nkan lo wo ti oruko re nje "Brabazon" wo nibe na.

Eniti o joko pekun ni owo osi ni Alakoso ise iwe irohin Eleti-Ofe, Ogbeni Taju Thompson, awon asoju Daily Times, Service, Tribune ati opo ti a ko le daruko won tan lo ba won lo lojo na.

## Oloye Akintola Ki Azikiwe Ni Iki Ayo

Oloye S. L. Akintọla lo kọwe ayọ bayi lati fi ki Dọkita Nnamidi Azikiwe wipe o tọ ki inu wa ma dun, ki a rin ki a si ma yan, fun ohun ti Ọlọrun ṣe fun wa. Nitorina on ki Azikiwe ati gbogbo awọn igbimọ rẹ pe nwọn ku oriretí ominira ti awọn ṣẹṣẹ gba yi, nitoripe, awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre kokẹrẹ ninu iru ayọ bayi.

Awa ti gbagbọ wipe ki a ni agbara lati maṣe ilu fun ara ẹni ni a npe ni ijọba toto ṣugbọn o dabi ẹni wipe o fẹrẹ pẹ lẹhin diẹ, sibẹ ṣibẹ, o dun mọ wa ni ti wipe awa mejeji lo njẹ anfani Ominira na nisisiyi.

Anfani Ominira na ti a njẹ loni, jẹ atunbọtan, ọgbọn, oye ati lakaye ti ẹgbẹ Afẹnifẹre ti fi ngbe nkan na bọwa, Ohun idunnu lo si jẹ fun wa wipe ọgbọn ati lakaye egbe Afẹnifẹre lo gbe awa mejeji de aye ti a wa loni.

Apẹrẹ ti a fi lelẹ lo mu awọn ara wa gbagbọ wipe, a to ẹniti o le ṣeto ijọba ara ẹni Ọwọ nyin a ran a o.

Alo o!
Ojo n Olukotun ko pa Ajagunna ?

USED LORRY TYRES
PRINTING PLANT-
CLOTHING
ORGANS-BAND INSTRUMENTS
We export Anything.
ALDERSHOT WAREHOUSES LTD., POUND RD., ALDERSHOT, ENGLAND.

Egbogi iyagbe ti o dara

O njẹki enia lagbara, ki o si ni alafia nigba gbogbo.

"HERBALAX - NDF"

Egbogi yi, a ma jẹki enia gbọnsẹ wọrọwọrọ, o nfọ inu mọ, ko si lewu, o nmu ẹjẹ enia ṣe pelu.

- x O jẹ egbogi kan ti o dara fun igbọnsẹ, ko si ni ko enia ninu.
- x O nwo gbogbo arun inu san, bi Ẹsanri, Igufẹ, Airi orun sun, tabi IṢAKA, Jẹdi-jedi, tabi Iju.
- x Ohun pataki lo jẹ, lati mojuto airi igbọnsẹ ṣe, ki a si pana rẹ.

Tete lọ ra tirẹ loni, -afara ko si. A ma nfun awọn ti o ba ra papọ ni itọwọ. Ẹniti o nta a ni :-

FRENCH MEDICINE STORES
8, MARTINS STREET, LAGOS. PHONE: 23264.

# E L E T I Ọ F E

A-NDU-WỌN KO SE WI L'BIỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

2⁸, Kosoko Street, Lagos "ELETI - ỌFE LAGOS"

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL. IX. NO: 533. LAGOS, SATURDAY AUG. 17. 1957


## A nje Ekuru ki o tan...

Ẹ tun ngbọn ọwọ rẹ s'awo, gẹgẹbi owe Yoruba, ni a fi ṣe ẹsin aṣayan ọrọ wa ọsẹ yi fun ẹnyin ọkawe wa nipa ọrọ rogbodiyan ilu Ọyọ, eyiti a se irohin rẹ si apakan iwe irohin wa ọsẹ yi.

Wosika wa ọsẹ yi, awọn agba-agba ati awọn ọdọmọde ilu Ọyọ ni a fẹ ba sọrọ lori akitiyan ti o ma nsaba ṣẹlẹ lorekore lati nkan bi ọdun mẹta wa s'ẹhin; Gẹgẹbi Ọyọ ti jẹ ilu iṣẹdalẹ lailai, ti o si jẹ ọkan ninu Olu ilu fun awọn Ọba ilẹ Yoruba, ko tọ, ko si yẹ k'i o jẹ wipe ilu Ọyọ ni rogbodiyan ko ni jẹ ki o roju lati ṣe eto tabi iṣẹ ilu, eyiti yio fa ilọsiwaju ilu

Awa ko fi dandan le ori ẹgbẹ kan ṣugbọn o yẹ ki olukuluku enia l'ọkunrin ati l' binrin, l'omọde ati agba mọ wipe asiko ti a wa yi ki iṣe asiko ere ṣiṣe tabi akitiyan fifa bikoṣe asiko iṣẹ ilu pataki ati irẹpọ wa, ki a le gbe ogo ilu wa yọ gẹgẹbi Orilẹ-ede ti a nlepa rẹ, lati sọ ilu wa di ijọba ominira.

Gbogbo hati-hati bi o ba ki o mu, bi o ko ba ki o bu lẹsẹ ti nwọn mba kiri nilu Ọyọ nisisiyi, ko le ṣe anfani kan fun wa, nitorina, a fi wosika wa yi gba ẹnyin enia wa ni imọran wipe ki Olukuluku lọ fiye denu, ki a gbagbe ohun to ti kọja, ki ale sowọpọ fun ite ilu wa.

## Se Ohun Gbogbo Pele-pele

Pẹlẹ-pẹlẹ ni arẹwa arin, jẹjẹ l'ọmọ ọlọla yan, igba onipẹlẹ ki fọ, awo onipẹlẹ ki ya. Ohun ti a fi ẹsọ mu ko mbajẹ, ohun ti a fi agbara mu lo nle ni lara kokoko.

Pẹle-pẹle ni ejo fi ngun ọpẹ igbin ko lọwọ, igbin kọ lẹse eso-esọ ni igbin fi ngun igi Gidi-gidi ko mọla, k'a ṣiṣe bi eru ko da nkan.


## Imoran Fun Enyin Abiyamo

Enyin abiyamọ ẹ wa ra ỌMỌRELA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama jẹ ki ọmọde ri orun sun daradara o dara fun otutu, ikọ ati orişirişi arun miran ti o ma mba ọmọde ja ni asiko ehin. Ọpọlọpọ abiyamọ lo ti lo egbogi yi fun ọmọ wọn ti wọn si sọ wipe o dara pupọ fun awọn ọmọde

ỌMỌRẸLA BABY MIXTURE

(Şile Meji Abọ 2/6d Fun Igo Kan)

O wa Lọdọ

COMMERCIAL MEDICINE STORES
(Qualified Chemist)

10, VICTORIA STREET, LAGOS.


## Werepe Oloro ko Sunwon

Lati ọwọ ỌLA ỌNATADE

Njẹ aiye ko nfẹ parun bayi? Awọn ologun ati am'oye ilu Jamani (Germany) sọ wipe ẹniti Şango (ọkọ Ọya) ba to'ju rẹ wọ'lẹ ni'le ẹrọ werepe oloro ti a fi nşe ọşe l'ogun, ti a npe ni Atọmik bọnbu (H-bomb) ti awọn alagbara aiye bi Gẹsi, Amẹrika ati Rọssia ndanwo kakiri sinu afẹgun - wọn ni awọn fẹ ki wọn da ọwọ rẹ duro nitoripe o le pa gbogbo aiye run ni ala-iro tẹlẹ.

Awọn ara ilu Japani ni ki a pana ki a si tun tẹlẹkun mọ ori ki a to fenu kan ọşẹ ti werepe oloro yi nşe si ara ọmọ enia ati ẹran. Wọn ni ko si ẹniti o le dun mọ lẹnu bi awọn ti awọn ti tọ oro rẹ wo.

Ọrọ na lọ bayi wipe nigbati awọn ilu Naijiria nsọkun, ti wọn si ngba awẹ alairi iyọ oyinbo ati bọta jẹ lọpọ to, nigbọn nkan bi ọdun kejila si igba yi, ni owurọ ọjọ kan ni awọn jagun-jagun ilu Amẹrika gbe ọkọ ofurufu wọn pẹlu werepe oloro lọ si ilu Japani kan, ti a npe ni HIROSHIMA. Ilu yi kun daradara, o si jẹ idi ati ile işẹ orişirişi. Awọn ara Amẹrika ko şalmọ bi ilu na ti jẹ-wọn si şe ikilọ wipe ki awọn Jepani ye ogun ja, ki wọn ma ba di ọni iparun, Jepani pe ọrọ na ni ọrọ awada.

Şangba fọ ni arọ ti wọn ju bọmbu oloro sile nitori olukuluku şẹşe de ibişe re niwọn nkan bi agogo mejọ ni, Ọiọmọ ko mọ ọmọ, enia ti o ku nlọ bi Ọkẹ-meta (60,000) awọn ti ko je oku ti ko je alaye enia je ọkẹ marun (100,000) Bi bọmbu yi ba ti fọ tan o di onigba-arun. O nsọ ọkunrin di okobo obinrin a di agan—eyiti o ba loyun inu a baje lesekanna.

Egbo re ki san bọrọ eniti raborabọ re ba bi o ti nşe igbe ọrun beni yio ma bi ebi, gbogbo irun ori a ma şi sile nigba nigba. Bi yọrọ eleje ti njade lenu beni oritifọ nşe tiro. Awọn oyinbo wa npe onigba-arun yi ni orukọ kan (Radiation sickness) Ọta nkan elemi ni o.

Awọn ọlọgbọn aiye ti o ba wọn şe ọna ti wọn fi kọ nkan eto idi re lọ wa fi ada kọri wipe awọn ko fẹ atọmik bombu yi mọ-nitoripe bi awọn ti nla mọlẹ beni nkan ti o njade ninu re nbaiye je Ẹnikeni ti o ba ti ni lati di ọmọ adọta ọdun laiye ri marun ni lati dinku ninu re bi won ba ti la bọmbu onigba-arun yi mọle Awọn lo mo nkan ti wọn kojọ sinu rẹ.

Gbogbo awọn ọlọgbọn aiye yi (World Scientists) şe iwe ẹbẹ ranşe si Amẹrika Gẹsi ati Rọssia Awọn Gẹsi ni ọrọ tawọn kole, awọn awo bi eyiti awọn na şe ti ni agbara to ni, Rọssia ni ọran ẹbẹ ko,

(Wo iyoku loju ewe karun)


No. 73/S 2/Vol. VIII/494

## Printing And Stationery Department-Vacancy For Senior Assistant Superintendent of Press.

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment to the post of Senior Assistant Superintendent of Press, Printing and Stationery Department, Western Region, Ibadan.

Scale of Salary: C (T.) 5: £1056 x 42-£1, 140.
The post is pensionable and the appointment will be on probation for three years Non-Nigerians will be considered for appointment on contract terms

For further particulars and Method of application see Western Region Nigeria Gazette No. 35 Vol. 6 Notice 705 of 1/8/57.

Closing Date: Overseas Candidates 22/8/57.
All other Candidates 29/8/57.

## Werepe Oloro ko Sunwon

(O bẹrẹ loju ewe kẹrin)

nitoripe bi a ti nṣọ lọwọ yi ni awọn njaa ti wọn na mọlẹ. Ju gbogbo rẹ lọ, bi awọn ko ba fi han awọn ọta wipe awọn ni iru nkan bẹ lọwọ; wọn ko ni slami ariwo ogun - jija.

Ibiti a wi l'ode yi-- nje aiye ko 'nfẹ parun bayi?

## Okunrin Fi Ailadie R'ago

IBADAN Owo awon olopa te okunrin kogbede kan, ti o ko orisi awon irin ise dani a gbo wipe kokuku je wipe nse lo nfi won se ise kan nipataki.

Ohun ti olopa mu okunrin na ni wipe, lona Apata Ganga, lasiko ti awon akowe ti o wa nibe ti lo sibi ise tan, ni okunrin ti a wi yi bere si dan kokoro kan wo lara ilekun ile kan. Nigbati o si, si, si ti ko se si o tun paro kokoro ni awon olopa ba fura si i, ni nwon ki i mole

A gbo wipe eru kokoro ni nwon ba lowo re. Adajo bere lowo re pe ile melo ni o ni? o si dahun pe ile mẹdọgbọn, nigbati awọn ṣiro awọn kọkọrọ nwọnyi, o jẹ mejilogun. Adajọ na tun bere, nibo ni awọn ile na wa?

o dahun pe, ọkan wa l'Ọja'ba, ọkan nisọlẹ Ijẹbu, ọkan ni Gẹgẹ. Adajọ lọ dan awọn kọkọrọ na wo nibiti o gbe wi, ṣugbọn ko ba lẹkun ibẹ mu. Ni adajọ ba sọ wipe ki o lọ si ẹwọn ọdun meji pẹlu iṣẹ aṣegan.

# Ija-gbore tun be sile ni Oyo



OYO. Irohin kan wa ni akiyẹmi ara wipe, Alaiyeluwa Kabiyesi Baba-lefin Ọyọ. Ladigbolu Keji, ni lati lọ bọ Oriṣa-Oko ni Ọja-Akesan ni agogo mẹwa alẹ ọjọ Sunday. Alafin yi, ẹniti o ti mo iru iwa ti awọn enia rẹ le hu, o ranti owe Yoruba kan ti o sọ bayi pe, Jakumọ ko rin lode ọsan, ẹniti a bire ko orin lode oru".

Nitorina, dipo agogo mẹwa alẹ, Alafin lọ bọ Oriṣa na ni agogo meje alẹ. Bi ko ba si ti awọn ọlọpa ti o ti hamọra ija tẹlẹ, ti nwọn si ba Alafin lọ sibi ojubọ oriṣa na lọja Akẹsan, ohun kan ko da duro wipe ki iru ija gboro ti o ṣẹlẹ ni ọdun 1954 maṣe tun ṣẹlẹ.

A gbọ wipe, ni gẹrẹ ti Alafin bọ oriṣa yi tan ti o bere si jo, ti o si nyọ ayọ lọ sile, ni ija tun bẹ silẹ nibiti Alafin gbe kuro nibiṣiyi. Ariwo ta, awọn obinrin nke; ọlọmọ fa ọmọ rẹ lapa, onilẹkun ti ilẹkun, awọn ọlọpa ibile ati ti ijọba wa wọya ija pẹlu awọn janduku enia nwọnyi. A si gbọ wipe boya awọn ọmọ ẹgbẹ Parapọ lo da ijọgbọn na silẹ.

Ọgbẹni Afọlabi, ti o nwa mọto fun ọba, nṣe ni awọn janduku nwọnyi ki mọlẹ, nwọn wọ ọ lọ sinu ṣọbu kan, nibiti ọkunrin kan ti nwọn npe ni Muili gbe nta'ja nwọn lu u tinu-tẹhin, a si gbọ wipe, Muili ti o ni ṣọbu na jẹ ọkan ninu ọmọ ẹgbẹ Parapọ.

Awọn enia ti ọwọ ọlọpa ba lojo na ni Muili Alabẹbẹ, Raimi Face, Alimi Ago ati Bandele gbogbe wọn lo si jẹ ọmọ ẹgbẹ Ọyọ parapọ. A gbọ pe awọn ọmọ ẹgbẹ Ọyọ parapọ, lo sungbalẹ si kotu ọlọpa wipe awọn ko ni kọ ohun ti o le tidi rẹ bọ, bi awọn ko ba fi ara wọn ti awọn timọle sile. Haba! ẹnyin ara Ọyọ, nigbawo ni ẹ o simi itiya nwọnyi ?.

Lẹhin ijagboro ti o ṣẹlẹ ni ọdun 1954, o digba mọkanle-logun ti ijagboro mbẹ silẹ ni Ọyọ ati ni agbegbe rẹ. Igba gbogbo ni ijọba nran ogun awọn ọlọpa lọ si Afin pẹlu ihamọra ija, boya aibamọ, awọn enia na le gbagbe ọjọ buruku ti ọdun 1954, tabi boya nwọn le daba lati wọ Afin. Ọrọ na koiti pari awọn ọlọpa si nwadi siwaju nipa ẹniti nwọn mu, ten mu pẹlu.

## Iwe Si Lemomu Ajakuta

Olotu,

Jọwọ gba mi laye lati ṣe itere yi lọdọ Alufa Lemọmu Ajakuta, oniwasi agan ti o ma nfigba gbogbo tako awọn Kiriyo. Njẹ bi a ba sọ wipe awọn Imale nṣe Egungun, mo rope iwọ Lẹmọmu ki yio ha jiyan? Duro! ngo ṣe alaye fun ọ.

Odidi alhedji oniwasi kan lo sọ fun wa pe didun ohun gẹgẹbi ti egungun, lati inu tira lo ti wa, O sọ wipe lọdọ awọn ti o ba mọ kewu ni pipe daradara, bi a ba fẹ ke Abusu Bilahi; oluwa rẹ ni lati dun ohun gẹgẹbi ti Egungun.

Ni akọkọ, ako fẹ gbagbọ ṣugbọn mo tun ri awọn alufa miran ti iyawo wọn nṣe egungun ni ọsan gangan, nwọn o fi ajiwọn dudu bojo ni ọsan ti awọn si fi funfun bori ni oru.

Njẹ iwọ Alufa Ajakuta, kilori sọ si eyi. Riwo, riwo, matu-ariwo! ya! ẹru, owo gbingbin His. Okoro, ọti yi dun, ayungba yungba.

Emi ni.
Ọjẹ Abẹgunrin
ọmọ Alagba

## Idahun si Ibere

OLOTU,

Gba mi laye lati ṣe itumọ ọrọ ti mo ri ka ninu Iwe Eleti-Ọfẹ ni ọsẹ ti o kọja ti wọn bere wipe "Aja agba ni igbo oke ijan mi titi."

Itumọ rẹ ni ibọn ṣakabula.

Oluwa jẹ ki a tun ri omiran o.

Emi ni
Z. Olo olaiyemọ




## Oloye Akintola ni Fenandopo



Awon ti a nwo ninu aworan yi, ni Oloye S. L. Akintola nilu Fenandopo nigbati o lo se iwadi nipa awon omo ile Nigeria ti nwon nko lo s'se nilu Fenandopo lati ile Ibo, ati ile Kalaba. Ogbeni Akintola ni awon Payan yesi bayi ti nwon si pe e si ipade kan pataki lati gbo lenu re, kini ohun ti o bawa sile Payan.

Oloye Akintola lo duro larin won ti o nsoro, yen awon oyinbo Payan, oyinbo Olopa, British Consulate ati awon enia nlanla miran lo joko yika, ti nwon si gba a ni alejo.

## Ijoye ti o se, ti oba ro l'oye (Apakeji)

Ọkunrin kan wa nilu Eko lasiko igba aiye ọba Dosunmu ti nwọn npe ni Faro. Ọgbẹni ti npe nwọn ni Faro yi lo jẹ Oye Ọjọra ti nwọn si rọ loye nitori aṣemaṣe rẹ. Kini ohun ti ọkunrun na ṣe, ti o di ọran si lọrun ?.

Awọn opitan sọ wipe edekoyede kan bẹ silẹ larin awọn ara adugbo Offin nilu Eko ati awọn ara Ijọra, nibiti Ọgbẹni Faro gbe jẹ oye si. Kaka ki Faro pari edekoyede na fun wọn nṣe lo ngbeja awọn ara Offin si awọn Ijọra. Ija na di nkan ti nwọn ni lati fi ada yanju rẹ funra wọn, ọpọ enia lọ si gbọgbọ nidi ọran yi. Eyi ni sababi ti awọn ara ilu Ijọra fi kọ ẹhin si Faro.

Nwọn mu ẹjọ rẹ lọ siwaju Ọba Dosunmu wipe awọn ati gbogbo awọn ara ilu Ijọra ko fẹ Faro mọ gẹgẹbi oloye Ọjọra nwọn rohin fun ọba ni ohun ti o ṣe fun wọn. Dosunmu ni ki awọn enia na tun lọ rohin bayi gẹgẹ fun ọba Goloba, awọn enia na si ṣe bẹ.

Ọba Goloba ranṣẹ si ọba Dosunmu, wipe; on gbọ gbogbo bi ọrọ na ti lọ ki ọba Dosunmu ṣe gẹgẹbi o ti ọ nipa rẹ. Eyi nidi rẹ ti nwọn fi gba fila oye kuro lori rẹ nitori ti o fi awọn enia tirẹ silẹ lọgbe nija, o si ngbe ẹni-ẹlẹni nija.

Nigbati ọba gba fila oye kuro lori Faro, o fi iga Ọjọra silẹ, o si pada sinu ile rẹ ni Idumọta lati ibiti o gbe ti lọ joye. Ṣugbọn Idumọta ko rọ ọ lọrun mọ gẹgẹbi ti atijọ, ẹnikan ko si tilẹ yẹ ẹ si mọ, paapa awọn ara Offin ti o gbenija ko bikita fun. Nigbati ẹgan ati tiju a pọ lo ba salọ si Ajaṣẹ. Lẹhin ọpọ ọdun awọn ijoye Eko bẹbẹ fun, ọba Dosunmu si tun pe e pada bọ sori oye rẹ. awọn ara Ijọra si fi tayọ-tayọ gba a.

# Alapara Ibadan nki yin o

OKE FỌKỌ
Ibadan

Mo niran owe awon baba wa kan ti o ni bi omode ko ba de oko baba elomiran ri a ni ko si oko ti o to oko isu baba on – toto oro na se bi owe. Sugbon awon baba mi ara Oyo ni mo fe ba soro omolebi lose yi.

Emi Alapara Ibadan ti de ilu Oyo ti pe nitoripe nko le se wahala o wo egbe - o ko wo egbe. Ni ti gasikiya nko tile mo iru egbe ti nko ba wo bi Oyo Parapo ni, bi Oyo Pawopo ni o, bi Isehin Pasepo ni, bi Fiditi Foriti ni, bi ara Awe we wopo ni, bi Ijaiye Jaiyepo ni, oro na ko tile ye mi rara. Sugbon mo lo si ilu Oyo ni aipe yi lati ba won se odun Orisa Oko, nitori olorisa oko ni iya mi - Orisagbemi ni oruko emi Alapara Ibadan papa. Osan gangan ni won we mi ni wonka ti mo di Imole apapandodo.

Bi mo ti de Oyo ni mo bere bi won ni Egbe Bomodekoku ki emi na ba le wo egbe na won ni ko si rara. Mo ni Egbe Olowololagba nko? Won ni eyiti o wa enu won ko te le mo won si ti ntuka kuro n' ilu ni okokan. Oro yi mu mi ronu pupọ. Nitoripe Egbe Bọmọdekoku ni o ma nṣe Bọbaiiroro ni gbogbo ile Yoruba ti mo mọ wọn si ni lati ma gbe awọn agbagba nitori ebin ọla

Bi mo ti de ọja Akesan ni mo ti mọ wipe awọn ọdọmọde ilu ko teriba fun agbalagba mọ nitoripe diẹ loku ki wọn tilẹ na baba Olorisa ati iya Olorisa de ilu. Ire bi ilu yio ti ṣe r'oju-r'aye ko ṣe su ni ọjọ yi. Emi Alapara fese fe; fila labarikada mi bọ sijọ na. Ọlọpa kan ti o sọrọ kelekele fun mi ni o ba mi mu. Ọba ni gba alayilara mo sa si Afin ọba Ladigbolu keji mo wa nmi hele - hele. Ọyọmisi pele pele o.

Ni ọsẹ ti o mbọ Alapara Ibadan yio sọ ọrọ Ọyọ yoku. Alapara Ibadan nki yin o.

# Payan yio tun bere si j'oba

SPAIN. Ni ọdun 1938 ni ọba ilu awọn Payan (Spanish) ṣ'aisisi ati ni ṣoro ti ọba awọn ti awọn npe ni Alfonso ku tan ni ijagboro nla kan bere larin awọn ijọba ilu na ati awọn alatako,, ijagboro ti a wi yi ko nṣe kekere, enia ti o ku ni di ijagboro yi ati dukia to ba jẹ, ko ṣe fi ẹnu sọ. Asẹhinwa-asẹhinbọ, ijọba ni lati fi ọhin silẹ fun awọn alatako.

Latigba na wa, ni awọn ko ti ni ọba mọ. Ṣugbọn General Franco ti o nṣe aṣiwaju awọn ẹgbẹ Alatako ti o jẹ wipe on lo ti nṣe alakoso ilu ṣe ndi arugbo, nisisiyi ni awọn fẹ bẹrẹ si ati ma j'oye ọba gẹgẹbi ti atijọ.

Ẹniti agbọ wipe awọn nfẹ fi j'oye ọba titun na ni Ọmọba Juan Carlos, o si jẹ ọmọ bibi inu ọba ti o jẹ gbẹhin; ọba Alfonso.

# Ojo Gbe Gada Lo

IGBAJỌ. Ojo ọdun ni ke si ibi ti ko de ni gbogbo agbegbe ilẹ Naijiria, o de oke o si tun de odo. Eyi ti a gbọ wipe o tun ṣe ni agbegbe odo Ọshun ni wipe, o gbe afara kan lọ ni oju ọna ti o lọ si Igbajọ ti a npe ni Agirimọdo.

Ọna yi ni ọpọlọpọ ara Igbajọ nba wọ ilu afi ki wọn tun gba Ọtan Aiyegbaju lẹba Oshogbo.

Isena yi nu ki onje awọn alakukọ ko le fi wọn ni ilu diẹ tobẹ ti de ile ati isọ wọn mọ.

# Olori Demo



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Ọlọrun – Nimbẹ olori ẹgbẹ Dẹmọ ilu Eko, on ni a gbọ wipe o fi ọwọ sọ aiya wipe, bi o ba ku on nikanṣoṣo ni Dẹmọ nilu Eko, on ko ni ba ẹgbẹ N.C.N.C. ṣe.

A tilẹ gbọ wipe oriṣiriṣi Dẹmọ lo mbẹ nilu Eko. Ọkan ti Makọli ọkan ti N.C.N.C. ati ọkan ti Oyekan.



## Ranti Awon Oku Orun

O yẹ ki a ma a ṣe iranti awọn oku ọrun wa, awọn ẹni rere ti o ti rekọja.

| | | |
|---|---|---|
| 1. | K. Ekemọde | 21/12/21 |
| 2. | Wababi Shitta | 11/3/33 |
| 3. | S. Majẹnrahun | 24/2/39 |
| 4. | James Ronbi | 9/2/42 |
| 5. | Adamọ Akẹju (Oloye Obanikoro) | 31/7/42 |
| 6. | Bello Alufa | 16/3/45 |
| 7. | Herbert Macaulay | 7/5/46 |
| 8. | A. L. Thompson | 20/5/46 |
| 9. | Lawyer A. Taylor | 26/9/47 |
| 10. | Bọlaji Martins | 9/2/52 |
| 11. | Asani Thompson | 14/9/54 |
| 12. | T. A. O. Savage | 14/4/56 |

## Esin Imale Ko Posi Lati fi Sin'ku

(O bẹrẹ loju ewe kini)

oku na lati ibikan lọsi ibikan.
(4) Ti o ba ku sinu ọkọ oju omi ti irin ajo na ba jẹ chua ti o jina bi irin ijọ marun lọsi mẹwa, ao pinu lati kuku ju si odo, ao kan a mọ posi ju sinu odo na. Eniti ariwi nwọnyi ko ba si fun ti o nṣe ilaju ju ti awọn Eni Ọlọrun lọ, on ṣe fifẹ lau. Nitori (Alkurani ni "waja tabah awa a".)

## Omo Oba Gesi Charles Fe Bere Ilewe



Omoba Charles, ti o nse akobi omo fun oba ti o wa lori oye yi, Oba obinrin Elezabeth Keji lo d'agba di eni odun mejo, o si nilati lo bere eko nipa Iwe ninu Ilewe Berkshire nibiti baba re Duke of Edinburgh gbe ti ko eko Iwe. Nigbati o ba di osu Nov 1957, Omoba na yio di omo odun mesan gere.

## James Egbuson m'ori bo

Ọga ọlọpa ti n pọn npe ni James Egbuson ti awọn ọlọpa ti fi sun ẹsun meje wipe o ngba owo-bamiṣe, owo ibọlẹ (Bribe) ti o ti wa ninu ẹjọ na ni Kotu Ganran (Azize) nilu Benin ni adajọ agba Ọgbẹni W. A. H. Duffus da ẹre lori gbogbo tipa-dọnin ẹjọ aromọ oriṣiriṣi ti awọn ọlọpa ro mọ Ọga ọlọpa Egbuson l'ọrun.

Adajọ sọ wipe lẹhin ti on ro arojinlẹ lori ọran ẹjọ na; on ni itẹlọrun wipe gbogbo ẹri ti awọn jẹ niwaju on, ko fihan pe ọdaran na ṣẹ si ọkọkan ninu ẹsun ti nwọn fi sun, ẹri irọ ni gbogbo awọn ẹlẹri jẹ ọrọ ẹri wọn ko si ṣe gbagbọ, nitorina ẹtọ ni ki a da silẹ ki o ma lọ l'alafia.

Aki Egbuson ku orire.

## Oma Oyekan tun fe gbe Ejo Iga Idunganran dide!

(O bẹrẹ loju ewe kini)

o bi ti ngbe Iga Idunganran agbe ibẹ gẹgẹbi Ọba Eko ni. Adele ni Ijọba gba pe a yan ni ọna ẹtọ, on l'o ni ẹtọ lati gbe inu Iga.

Boya Owo irin cse kolti tan lọwọ rẹ ni.

## ANFE ASOJU

A nfẹ Aṣoju fun Iwe Irohin wa Eleti-Ọfẹ lati fi kun awọn Aṣoju wa ni awọn ilu ti a darukọ ni isalẹ wọnyi:-

Abẹokuta, Ijebu Ode, Ijebu-Igbo, Ile-Ifẹ, Oshogbo, ati Port Harcourt.

Ẹ kọwe si Olotu Iwe Irohin Eleti-Ọfẹ, 28, Kosọkọ St. Lagos.

## Omo'ba Gesi, mbo wa be ile Nigeria wo



Ọkan ninu awọn ọmọ ọba ilu Gẹsi, ẹniti Gomina agba nilu Eko ti ranṣe si wipe ki o wa bẹ ilẹ Nigeria wo, yio de silẹ yi ninu oṣu November 1957.

Ohun pataki ti o mbọ wa ṣe ni wipe, o mbọ wa si ile ẹkọ giga ti iṣẹ Iwosan nilu Ibadan ati ile ẹkọ iṣẹ-ọwọ ati ọgbọn ori nilu Zaria, yio si ba wọn ṣe isin ọgọrun ọdun ti nwọn ti da ijọ C.M.S. silẹ lori ode Ọya nilu Onitsha.


M.B.T
(MAGIC BLOOD TONIC)



Iná dé, òkùnkùn paradà. M.B.T dé, òkùnrùn ṣò lọ. Ẹ̀jẹ̀ dúdú sárẹ́, òyì pọ̀ṣẹ̀ṣẹ̀. Àlá buburú wọ'gbó. Àìlèsùn r'ẹ̀hìn-ẹ̀kùn. M.B.T. kógùn-ẹ̀jẹ̀ ti nmú ni jẹun b'ìkà, amú ni yàgbẹ́ bi ọ̀kùn, amú ni tọ̀ bi àkèrè. Abiwérẹ́ fàboyún, agbẹ̀jẹ̀dà pawọn abiyamọ. Ahọ́n-dúdú, ẹsẹ̀-wíwú ati àiyà-jíjá ko ṣi ẹ́niti nlo o.
4/6d pẹ̀lú 1/6d owó-ọkọ̀.
ARADAN STORES P.O.Box 2 EBUTE-METTA.


Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosokọ Street P. Box 457 Lagos Phone 23590